Ao wa ako eiye oga ooye kan ao lo lorun pa ao wa ti ikode bo ni enu ti yio wonu re dada ati odidi atare kan, ao ko sinu isasun ao jopo ti aba jo tan ao lokuna dada ninu isasun yi ao wa fi te odu ejiogbe ninu isasun yi ao wa pe ohun re si, OHUN RE….. emi………………. OMO………………. MO DARAPO MO EYIN EILEYE FUNFUN LATI ONIYI LO, EJE KIN MARI YIN LOJUKOROJU, MO FUN EYIN NA LAYE LATI WA MARI EMI…………………. OMO……………. NI IBUGBE MI, TABI NIBIKIBI TI MO BA WA, TI OUNKOUN TABI ABURU KAN BA FE SELE SI MI NI IBUGBE MI TABI ABGEGBE MI TABI NIBIKIBI OKUN OJO MARUN NI KIE ETI WA MA SO FUN MI, KI ESI MA WA SO NKAN TI MA SE SI TI ABURU NA KOFI NI SELE, KI ESI BAMI SHI ONA IRE FUN MI KI GBOGBO WALA ILE AIYE MI DOPIN LATORI AROMODOMO MI KI EMA TARI ORE NLANLA SI ODO MI, LATI ONI LO, GBOGBO ENIKENI TO BA GBERO IKU SI MI EJE KI WON MA KU NISOJU MI, GOGBO ENIKENI TO BA NGBERO ABURU SI MI ABI TI O FI OJU BURUKU WO MI, EJEKI OJU WON MEJEJI KO FO DANU, GBOGBO AGBARIJOPO AWON ELEIYE DUDU ATI AWON ELEIYE PUPA E,MAJE KI WON RI MI……………………..OMO……………… FI DAJO O GBOGBO ENIKENI TOBA FE GBA ABODE,TABI IYAWO TABI OMO TABI EBI, E,JE KI WON MAFI ENU WON KA BOROBRO FUN MI NIO, KI ABURU ATI AJALU MA SELE SI WON NIO, KI ABURU KANKAN MA SE AWON OMO MI ATI AYA MI ATI EBI MI TI WON BA NIFE MI DENDENU, KI ORO MI MADI OMO INU OKA NI SE IKU PA OKA, SUNGBON TI OBAJEPE EKO NI BAMI SE GBOGBO NKAN TI MO SO KALE YI, KI E,MA WULE YOJU SI MIO]…. Leyin ti aba wi gbolohun yi si ebu ogun ti ajo yi ti afi te odu ejiogbe sinu isasun tan ao wa ro gbogbo ebu yi sinu ado ijamo kan ao wa olele elepo meta ati

akara elepo meta ati ekuru funfun ti ko ni iyo ti koni epo meta ao wa ko sinu awo ipese ao fi ado yi le lori ao wa si enu ado yi sile ao wa gbe ipese lo si eyinkunle wa ni agogo mejila ale,[12,oclock.night] ao gbe kale si ibe ti oba di ni owuro ojo keji ao lo gbe ipese ti won ba jekun ao wa jopo pelu ado ti fi sinu ipese yi ao wa ro sinu ado miran ao ma fi fo eko tutu mu larolaro ni ojo keta keta sirawon fun odidi osu kan gbako [AKIYESI.POATAKI. akogbodo lo ogun miran yato si ogun yi beni akogbodo sunmo obinrin] ao pe ohun yi si ipese yi ki ato gbe ao tun ma pe ohun yi si nigbakigba ti abafe lo ao tun ma pe ohun re si ODAJU BIKU,

IFA OSE AJEOGUN TI,JI OGUN TOTI KU NINU ARA TODAJU BIKU

Ao ju eja ojiji ooye kan sinu odo ao ko ewe esisi tutu oojo funfun le lori, ao gun papo ti yio kuna dada ao wa pomo ose dudu ninu odo ao tun gun mo ose yi dada, ninu odo, ao wa mu eja ojiji ooye imiran si isale igba olomori kan abi ike funfun kan ao wa ko ose yi le eja ojiji ooye yi mole ao wa fi omori re de ao lo gbe leyin ojo keje ao ma we yato si ojo wenesday ati Saturday odaju pe gbogbo ogun toti ku ninu ara wa ni yio ji ti yio bere sini sise ODAJU BIKU,

IFA TI OBINRIN FI BI OMO NI IRORUN

Ao wa ogiri ti oba la enu sile ao bu iyepe otun ati osi ni ibi to la enu ni sale re ao lo kuna dada ao wa po papo mo ori ao ma fi pa ori oko wa ba obinrin oloyun na sun odaju pe yio bi ni irorun ODAJU BIKU,

IFA AKO OUNMO TODAJU BIKU

ao wa okan ako aja tutu oojo kan ati itana logunsese ati itana rere ao ko sinu ape ao jopo, ao lo kuna dada, ao wa mu eiyele fufun kan, ao pa ao ko ifun re danu, ao ge ao fi omi gbigbona bo jina dada ao wa da ebu ti ajo yi lelori ninu isasun ao fi se aseje yi je ,ODAJU BIKU.

IFA ASEJE OWO TODAJU BIKU

Ao wa ewe abamoda tutu merindinlogun,[16] ati ewe owu akese merindinlogun tutu,[16] ati egbo akere jupon, ao lo gbogbo re papo ao fa da sinu ape kan, ao wa pa okete kan, ao ko ifun re danu ao ge wewe ao bo jina ao da sinu abo kan ao tun mu igbin ao fi omi gbigbona bo jina ao yo kuro ninu ikarahun re ao ju ikarahun nu si igbo ao wa mu eran igbin bibo yi ati gbogbo eran okete yi ao ko sinu ape pelu awon eroja ti alo kuna ti afada sinu ape yi ao lo ata ijosin eyo mesan,[9] ao tun da le lori ao fi iyo ati epo si ao se laseje ti oba jina ao so si ori osuka kan a ao wa fi iyere osun te gbogbo odu ifa merindinlogun si inu nkan tofe dada ao wa pe ofo,re si… OFO,RE… AJIKAWO OJI KUTU KUTU BA OLA NILE, OSUPA TINU AJERE IDE LA WA SI ILEAIYE, OUN DAN YINRIN YINRIN KALU, IFA OTO GEE BAI KI O WA TAN INA OLA TI EMI……………………OMO………………… FUN MIO, IFA TA KAN KAN KI O GBERA NILE KI O WA FI ADE OWO BABA RE DE EMI…………………OMO……………….. LORI O,NITORIPE BI ABAMODA BA FI ORI BALE AYE,E, BI ABAMODA BA FI IDI KANLE AYEE, TAKESE NI SE LAWUJO OWU, AKEREJUPON O O O O O O O, ORUNMILA OTOGEE KI OWA LA EM…………………….OMO…………………… LATI ONI LO. EWU KI OWA LO HU IRE OWO NLA,NKA, ATI GBOGBO IRE AIYE WA FUN MI O, NITORIPE BI IGBIN BA DA ENU DE ILE AJE IFA ILE, ABOTAN NI ORISHS NBO IDI IGBIN, ODU MERINDINLOGUN KI LA ENIYAN TI, ODU MERINDINLOGUN O O O O O O, KIE KORAJO WA LA EMI……………………..OMO…………………… KIA,KIA, LATIU ONI LO, ODAJU BIKU

IFA IMULE AWON ELEIYE TODAJU BIKU

Ao wa odidi eiyele funfun ooye kan ati oga ooye kan ati obi ifin oloju mefa kan ati obi ipa oloju mefa kana ati eso ido,[201] ati eso werenjeje,[201] ati ojulowo aso iwaji funfun opa kan ati ewe afeloru tutu oojo ati igba olomori kan ati odidi atare kan, SISE,RE… ao ko gbogbo awon eroja yi sinu igba yi ao fi omori igba yi de ao fi aso iwa ji opa kan we gbogbo ara igba yi ti ibikan,kan ko ni han sita lara igba yi rara, ao wa so enu aso iwaji funfun ti agbe igba sinu re yi pa ao ao wa gbe sinu ape ao jo ti o ba jo tan ao lo kuna dada, ao wa ro gbogbo ebu ti ajo yi sinu ado ato kan ,tabi igo funfun ao tun ran apo aso funfun kan ao ma ju ado yi sinu re, ao ma gbe ko, ao ma fi fo odidi eko elewe kan mu ni alale, ti ao ni jade sita mo, ODAJU BIKU,

IFA AFOSE MAYIHUN TI AFIN BERE OWO LOWO ENIYAN ABI MANAGER TODAJU BIKU

Ao wa siri eso yerepe kan ati odidi atare kan ao jopo, ao lo kuna dada ao ma bu si ori ahon wa ba eniyan soro, ODAJU BIKU

IFA AWURE OLU BASIRI OLA TODAJU BIKU

Ao wa odidi ori ijimere tope dada kan, ati ori obo kan ati ewe ogede agbagba ti alo ja fun rara wa ti ko kanle, ao jo papo pelu odidi atare kan, ao ma fi fo odidi eko elewe kan mu larolaro ni idaji kutukutu, lai ti soro si enikankan, ODAJU BIKU,

IFA AKOYA TI AFIN DA SERIA LATI JE ENIKENI TO BA YA IGBE KALE SI [ILE ISE,ISO,SHOP] WA NI IYA TODAJU BIKU

Ao wa odidi oga ooye kan ati oko atare kan ao fi sinu ape tuntun ao jopo ao lokuna dada ao wa ro sinu ado ato kan ao di ni enu pa, ao wa da orire kodo ao lu nidi ao fi nkan dipa, ao wa gbe pamo, LILO,RE,… ti eniyan ba ya igbe si enu ona ile wa tabi enu ona [ile ise tabi shop]wa, ao lo gbe ado yi ao wa shi ado yi lenu ao to ebu die sori igbe yi ao di lenu pada, ao tun shi idi ado yi, ao jo ebu die si ori igbe yi,lati idi ado yi ao tun di idi ado yi pada ao wa gbe ado yi sinu awo funfun tabi igba olomori kan, ao mu ado yi, ao de egbe re ti yio sun kale sinu igba yi tabi awo yi, ao was hi idi ati enu ado yi kale ao wa fi omori igba tabi awo yi de pada ao lo gbe pamo [AKIYESI PATAKI… EGBE ADO YI NI AO FI LE ILE NINU AWO]odaju pe eni to ya igbe yi yio fe ya igbe ayaku, ti yio fe le ya gbogbo ifun inu re …ERO,RE… TI WON BATI WA BE WA TI ATI GBA EBE WON AO GBA NKAN TOBA WUWA LOWO WON AO DOGBON BU OMI SINU ABO KAN,KO MU AO WA LO SI IBI TI AGBE ADO YI, SI AO LO DI LENU ATI IDI PADA] odaju pe lesekese igbe yi ma dawo duro lesekese ni o, sungbon beru olohun mafi seka o,ODAJU BIKU,

IFA FUN ALEKO TODAJU BIKU

Ao wa ori ejo sebe kan ati ori alabahun ati odidi atare kan ao jopo ao wa lo ebu ogun ti ajo papo yi mo ogidi ojulowo etu ibon gidi ao ma fi fo eko tutu mu larolaro ODAJU BIKU

IFA ATUDE TOGBONA TODAJU BIKU

Ao wa eso werenjeje merindinlogun,[16] ati eso ido merindinlogun,[16] ao lo papo mo ose iwe ekan soso, ao tun gun dada ninu odo dada ti oba di ni ale patapata ao fi ose yi sori kainkain ibile kan ao mu epo pupa ati adin ati ori ao po papo dada ao fi pa gbogbo arawa latori dele ao lo we ODAJU BIKU

IFA EYONU TODAJU BIKU

Ao wa ewe ewuro ati ako alanga kan ati epo obo ao ko gbogbo re sinu ape ao jopo laisi atare nibe ao lo kuna ao ma bu die,die sinu oyin gidi ao ma to la ODAJU BIKU

IFA TI AFIN PADE AWON ELEIYE TODAJU BIKU

Ao wa iyepe orita meta ni ona mefa, ati alakan ti arin pade loju ona nigba ti aba nrin lo loju ona, eyo kan,[1] ati oga ti arin pade loju ona nigba ti aba nrin lo loju ona eyo kan,[1] ati odidi atare kan, ao ko gbogbo re sinu ape ao jopo ao wa ro ebu ti ajo yi sinu ado kan ao fi igi afeloru ati ojulowo iye awon agba kan di enu ado yi, LILO,RE…… ti aba fe pade awon eleiye ao gbe ado yi dani ao bo sita gbangban tabi orita meta ni ago kan oru ao ka ese osi wa ro soke, ao si enu ado yi ka le, ao wa ma wi awon GBOLOHU YI SI………… IBA OOO [3X,times] EYIN IYAMI OSORONGA, EYIN EILEYE DUDU ABARA BATIBATI ATI EYIN ELEIYE FUNFUN ABARA BATIBATI, E, MA MA KU IPADE ANA O O O O O, EYIN ELEIYE LENI KI NWA PADE YIN NI ORITA META ISALU AIYE, NIBI TI ETI NI KI WA BERE ORO,…. [ao se alaye bi oro na sejel]LOWO YIN LORI ORO ………………..OMO……………… SE KI NMA SO LO, [AO GBO OHUN KAN TI YIO SO FUN WA PE KI A MO SOLO] BI WON BA TI NI KI AMO SO LO, AO WA BERE SI NI SALAYE ORO NA LO, ABA TI SALAYE ORO NA TAN AO WA KA ESE OSI WA SI LE AO WA DE ENU ADO YI PADA, AO PADA SI ILE, [AKIYESI PATAKI…. NKAN TI WON BA TI SOPE KI ASE LA GBODO SE O, ODAJU BIKU,

IFA OSE EYONU AIYE TODAJU BIKU

Ao wa asin gbigbe kan ao gun lori olo kuna dada, ao ao ko sibi kan,ao tun wa lo ewe afeloru tutu kuna dada,ao tun fa si bi kan,ao tun lo epo obo na kuna dada, ao tun ko si bi kan, ao tun lo ewe botuje fufun tutu kuna dada, ao tun fa si bi kan ao tun lo ewe oriji tutu kuna dada, ao fa sibi kan ao, wa po gbogbo re papo mo ose dudu dada, ao wa ko ose yi sinu ewe lapa,lapa funfun, tofe dada kan, ao ma bu ose yi we ni alale pelu omi gbigbona, ODAJU BIKU,

IFA ASIRIBIBO TODAJU BIKU

Ao wa ewe sawerepepe tutu ati irun abe obinrin pelu [owo200.naira] tuntun kan,SISE,RE…. ao fi oti chinapp gbo ewe sawerepepe yi sinu igo kan ao wa lo irun abe obinrin yi, pelu 200.naira kuna dada ao ro sinu igo oti chinapp ti afi gbo ewe sawerepepe yi ao ma mu ni araro kutukutu haihai, ODAJU BIKU,

IFA PESE AKOYA TODAJU BIKU

Ao wa ekuru funfun odidi kan ao fi gi run sinu awo sobi ao wa lo epo bo die ao da le lori ao wa SOPE ……………………. OMO………………. LONI KI FUN EYIN ELEIYE LEWOO JE, MONI E KI JE , ONI OUNJE YIN NI, ONI KO SI NKAN TI ELE SE FUN OUN, O MO PE E, KI JE O, WA FUN YIN JE, MO FE KI E BAMI JE NIYA, KI E BAMI DA ISE RE RU, KI E BAMI DA GBOGBO IGBESI AIYE RE RU, LATI ONI LO KI IGBESI AIYE RE BERE SINI BAJE, KI GBOGBO NKAN DUKIYA RE KO BAJA ,KI OMA RI ALANU RARA, [AKIYESI PATAKI… akogbodo fi owo wa run ekuru yi igi ni ao fi run igi na ni ao fi po epo obo mo ekuru yi ninu awo sobi yi owo wa ko gbodo kan ooo,leyin na ao wa gbe ipese yi losi orita meta ao gbe kale sibe ao pada sile wa ni ale ni dede[12,30] agogo mejila abo, ODAJU BIKU,

IFA APE IFERAN TODAJU BIKU

Ao lo ja ewe owuro tutu oojo eyo meta,[3] ati ewe ogbo tutu oojo meta, [3] ati eni agemo, pelu odidi atare kan, ao jo gbogbo re papo ao pomo ose dudu die ao wa ko ose yi si oju gilasi iwoju tuntun kan, ao wa mu igi tere kan abi igbale ao fi te ejiogbe si ori ose yi pelu oruko [OBINRIN TABI OKUNRIN NA] ao ma we ose yi ni alale pelu pipe ofore…. OFOR,RE….. EWURO LONI KI IWO ………………….. OMO………………. MU TEMI RO,[3Xtimes] OGBO LONI KI IWO ………………….. OMO……………….. MU TEMI GBO,[3Xtimes] OJU ALANGEMO KI SHI KURO LARA EWE,[3Xtimes] KI OJU IWO ……………………… OMO ………………….. MA KURO LARA EMI……………….OMO……………… LONI O, KI OMU TEMI RO KI OMU TEMI GBO , ao ma we sun lalale ODAJU BIKU,

IFA EBE AWON AJE TI SHINA ORE TODAJU BIKU

Ao wa isu gbegbe ati epo obo ati ewe afeloru tutu oojo SISE,RE…. ao lo ewe afeloru yi lori olo ti yio kuna dada ao tun lo epo obo ti yio kun na dada, ao wa po mejeji papo mo, ose dudu, ao wa ko ose yi sinu odo, ao be isu gbegbe ao kosi ao gun papo mo ose yi kuna dada, ninu odo ao wa ko ose yi sinu igba tabi ike funfun olomori kan ao ma bu ose yi we pelu pipe ofo,re ..OFO,RE,…. AKI FI ISU GBEGBE BO IFA, AKI FI ISU GBEGBE BO ORISHA, ILE NI AJENGBE, ILE NI AJEOBALE NGBE, AJE KI JE OBO, EYIN OMO ARAIYE EFI ENU WA MI KAN, KI EWA FI OWO NLA,NLA SANU EMI……………. OMO……………. LATI ONI LO, DAJU BIKU,

IFA FUN NKAN OMO OKUNRIN TOTI KU PATAPATA TODAJU BIKU

Ao wa akuko adie ooye kan ao fi gbongbon lupa lekan soso, ao wa fi obe tomu dada ge ori akuko adie yi ni ekan soso, ao wa ju ori akuko adie yi sinu ape pelu odidi atare kan ao jo papo ao lokuna dada ,ao ma fi fo odidi eko elewe kan mu die,die [AKIYESI PATAKI… ENI TO FE LO OGUN YI KOGBODO JE NINU ARA ADIE YIO, AO FI SE SARA NI O, ODAJU BIKU,

IFA ETUTU EBE AWON ELEIYE TODAJU BIKU

Ao lo ra odidi obuko dudu kan,[1] ati ewe ajeobale tutu oojo [201] ati ewe ailu tutu oojo,[201] ati odidi atare kan, SISE,RE…. ao pa ao sun ara re nina sungbon ako ni sun ori re ni ina, ao ge ori re ao toju ori re pamo ao Ko ifun re danu ao wa ge gbogbo eran yi kekeke, ao wa lo gbogbo ewe yi lokankan ati atare yi ao wa la enu ori eran yi ao ko gbogbo awon eroja ti alo yi si enu ori eran yi ao wa fi ogidi ojulowo aso iwaji we ori eran yi dada ti ibikankan ko ni han sita mo lara ori eran yi, ao wa gbe ile ti yio jin koto sibi ti ati ati fe ki awon eleiye dari ore wa si ti afe ki ore wa ma wa bawa nibe bi [ILE WA TABI ILE ISE WA] ao wa gbe ori eran yi sinu koto ti agbe yi ao w ape ofo,re si ki ato bomole ..OFO,RE….. AJE ATI AJEOBALE NI WON JIJON GBE PAPO, TI WON KI FI ARAWON SE NKAN,KAN, KI AJE O MALE FI EMI ………………OMO…………. SE NKAN,KAN, KI AJE ATI OSO MALE FI ABURU AIYE KAN,KAN KAN EMI………………OMO……………. LATI ONIYI LO, ORE OWO NLA,NLA NI KI E MA DARI SI ODO EMI………………..OMO…………… LATI ONI YI LO, NITORIPE AKI RI IRAN LARA EWE ALUKI OSO ATI AJE O MA SE RI INU BURUKU BI SI MIO,OJURERE NI KI WON BERE SI NI FI WO MI LATI ONI YILO ao wa boi ori eran yi mole, ODAJU BIKU,

IFA ASEJE ASIRIBIBO TODAJU BIKU

Ao wa ewe tonaposo tutu ogorin,[80] ati iyere ogorin,[80] ati iru woro ogorin,[80] ati igbin nla merin,[4] aofi omi bo igbin mererin jina dada ao yo ikarahun won danu ao ge igbin eyo kankan kekeke si ona ogun,[20] apapo gbogbo igbin yi yio je ogorin,[80] SISE,RE… ao lo gbogbo ewe yi ati iru woro yi,ati iyere yi ao fa da sinu isasun ao ko gbogbo igbin ti age kekeke si ogorin yi sinu re ao fi epo pupa si, [AKIYESI KOGBODO SI IYO NIBE O] ao se lai fi iyo si rara ti aseje yi ba jina ao so sori osuka aso funfun kan, ao ro aso funfun modi ao te so fun kale, ao sun lori re, toba di ni [ago kan abo oru,1,30.am] ao wadide ao wa fi efun te ifa ejiogbe sinu awo prese kan, ao wa pe ofo,re si,..OFO,RE…… ASAPUTU PAJE NI ORUKO TI ANPE IFA, AJUWARA SOLA NI ORUKO TI A NPE ESU ODARA, OJINI KUTUKUTU OWURO GBA APO OLA MU NI ORUKO TI ANPE IWO SOPANNA, EYIN METETA LE RU BIGBA AJE WA SI ILE AIYE, EYIN LE SOPE ENIKENI TO BA BAYIN MULE OJU AJE KAN OGBODO PON LODE AIYE,EMI…………………… OMO………………… WA BA YIN MULE LONI E MAJE KI OJU AJE KANKAN PON MI MO LATI ONI LO, EFUN LONI KI E WA FUN MI NI OPOLOPO OWONLA,NLA NI ONA OGOGORIN, NI ONA OGORIN LOPOLOPO, NITORIPE TANAPOWO KI TAN INA TIE TI O, IFA KI O WA LA MIO, NITORIPE BI ONIRU BA SE IRU TAN AGBE RU NI, KI OMO ARAIYE FI ORI ARAWON RU ERU BOWO NLANLA WA FUN EMI…………………… OMO ………………… KI ARA OMA YA WON LOKUNRIN ATI OBINRIN ATI OMODE ATI AGBA ATI AWON OLOWO NLANLA KI WON MA WA FI OWO NLA,NLA SE MI LANU, NITORIPE BI ARA BAYA IYERE LEWE, ARA AYE LEGBO, AYA NI GBOGBO ARA O, IGBIN AKE, IGBIN OKO, IGBIN ARA, IGBIN APA, OJU KAN SOSO NI WON PANUPO SI JEUN O, KI IRE GBOGBO KO PANUPO SI ODO MI O, EFUNTADE, EFUNTAYO, EFUNAJOKA O, KI EMI………………OMO………………… KI DI OLOWO NLANLA, KI GBOGBO OMO ARAIYE MA SE MI LANU O,, NITORIPE TIFA TIFA NI AJE IGBIN KI EMI………………….. OMO ………………… JE IFA LODO GBOGBO OMO ARAIYE O, EJIOGBE WA LO GBE IRE OTUN ATI TOSI WA FUN MI O, [AO SE IWURE, ADUA] si dada Ao ko gbogbo re je le kan soso ao lo sun pada[IKILO PATAKI ao gbodo je iyo ni ojo ti aba je ase je yi fun odidi ojo meje gbako, aki je iyo o, aki je iyo fun ojo meje, ODAJU BIKU,

IFA ASETA TOGBONA TODAJU BIKU

Ao lo ja ewe kewe tutu to ba hu si ori sare oku ti won ko re lori, ao lo kuna dada ao po mo ori dada, ao ma fi pa idodo wa diedie, odaju pe bi enikeni basa si wa abi pe oriwa yio ku iku ojij ni ODAJU BIKU

IFA ISORI MADARIKAN TODAJU BIKU

Iye agbe kan ati iye aluko kan ati iye odidere kan, ati epo apa ati epo iroko, ati epo oruru, ati odidi atare kan,ao jo gbogbo re papo, ao ro sinu sere kan, ao pa akuko adie funfun kan, si ara ado sere yi, ti ao ro eje re si ara sere yi, ao yo irun abiya adie yi, ao lemo ara sere yi, ao gbe sinu awo funfun kan, ao je ki ategun fe si sere yi lara dada, ki eje yi gbe mo sere yi lara ati irun abiya adie ti ale mo lara yi, ao ma gbe ko ara ogiri kotun gbodo kan ile mo, LILO,RE…. ti aba fe lo ogun yi, ao lo re bole lori iko lara ogiri, ao wa to ebu die si ori atelewo wa aofi te odu ifa ejiogbe sinu awo perese kan, ao wa pe ofo,re si,..OFO,RE…. WON PE ORI AGBE AGBE NDA ARO KUN ARO, WON PE ORI EMI ………………… OMO………………… MO NI OWO KUN OWO, WON PE ORI ALUKO ALUKO NKUN OSUN MO OSUN, WON PE ORI EMI ………………….. OMO ………………… MO NI OLA KUN OLA, WON PE ORI ODIDERE ODIDERE SE IKODI YEBEYEBE, WON PE ORI EMI …………………….. OMOI ………………… MO SE ORI RE KUN ORIRE, WON PE ORI OSE OSE FIN SAN RA, WON PE ORI EMI …………………… OMO ……………….. MO FI NI OWO REPETE, BI OMODE BA DARISO IROKO IROKO AKO, BI OMODE BADARISO APA APA APA, BI OMODE BADARISO ORURU ORURU ARU LO, ao wa da ebu ti afi te odu eji ogbe ti ape ofo si yi sinu abo kan ao fi fo eko odidi kan mu pelu omi die ao gbe mu, ODAJU BIUKU.

IFA EBU ASRIBIBO ASINA TODAJU BIKU

Ao wa igbin agbonu kan, [1] ao wa jo omi idi igbin yi sinu ape ao yo igbin yi kuro ninu ikarahun re, ao tun ju eran igbin yi sinu ape nibi ti ajo omi idi re si, ao ju ikarahun yi si igbo, ao wa lo epo obo kuna dada, ao da sinu ape ti ajo omi idi igbin si ati eran re ao wa tun ju eiye adan kan le ori awon eroja ti ako sinu ape ao wa jopo lai si atare nibe ao lokuna dada, ao wa ro sinu igo kan abi ike olomori kan, ao depa ao ma bu die die fi fo eko mu ni arolaro, ODAJU BIKU,

IFA IPARA ANU TODAJU BIKU

Ao wa oku oga kan ao fi ko owu alantaku ti yio bo ni gbobo ara, ti ibi Kankan ko ni han mo lara oga yi, ao wa jopo pelu odidi atare kan, ao lo kuna dada, ao wa fi ebu ti alokuna yi te ifa odu ejiogbe sinu awo perese kan ao pe ofo,re si ..OFO,RE,…. BI IDAN BI IDAN NI OGA FI NGBA ASO ALASO BORA, BI DAN BI DAN NI ALANTAKUN FI RAN OWU RE, BI DAN BI DAN NI KI EMI ………………….. OMO ..,…………………… MARI IRE OWO NLA,NLA GBA LODO OKUNRIN ATI LODO OBINRIN ATI LODO AWON OLOWO NLA,NLA ao wa da sinu ipara ao po papo, ao ma fi para ODAJU BIKU,

IFA FUN IKO TONI AGBARA TODAJU BIKU

Ao wa ewe areyin kosun die, ati roro ogede agbagba, ao gun papo, ao fun omi re si inu igo kekere kan, abi ike olomori kan, ao ma muni sibi kan sibikan, odaju saka iko na yio pora, ODAJU BIKU,

IFA FUN IKIYA TODAJU BIKU

Ao wa okuta sango, ao ju sinu ina ti oba tipon togbona dada, ao wa ju sinu epo pupa ti oba tutu, ao yo kuro ninu epo yi, ao wa da epo yi sinu ekuru funfun, ti ati fowo run kale sinu abo, ao pomo, ao wa je, ODAJU BIKU,

IFA FUN ARA RIRO TODAJU BIKU

Ao wa egusi inu eso iyalode funfun topo dada, ao lomo ori ao ma fi pa gbogbo ara wa , ODAJU BIKU

IFA IDAKOLE TODAJU BIKU

Ao wa odidi iwo igala ao ge wewe si kekeke, ati obi abata fufun mewa,[10] ati obi pupa mewa,[10] ao jo gbogbo re papo ao lokuna dada ao ma bu si ori atelewo wa ao ma la ni gba ku gba, ODAJU BIKU,

IFA AYETA IBON TODAJU BIKU

Ao wa ota inu iroko, ao ko sinu odo, ao ma gun eyikeyi ti oba ta danu sita nibe, ao ma sa sibi kan, titi ti ao fi gun tan, ao wa ko gbogbo eyi to ta danu yen, ao ko si ori olo, ao lo kuna dada, ao ma fi fo eko elewe mu nigbakugba, eyi to wa ninu odo, ao lo danu si ori aki tan, ODAJU BIKU,

IFA FUN INU RIRUN TODAJU BIKU

Ao wa alubosa onisu funfun ati baka, ati iyere die, ao gun papomo ose dudu, ao wa su ose yi rodo rodo, ao ma ju eyokan si enu, ao ma mu omi gbigbon le, abi eko gbi gbona le lori, ODAJU BIKU,

IFA ASEJE AGELEPOTA MADARI KAN TODAJU BIKU

Ao wa egbo igi wowo, ati iyere ati iru woro, ati igbin agbonu kan,[1] SISE,RE,.. ao pa igbin yi, ni idi, ao fa eran igbin yi, yo jade lati idi, ao wa lo gbogbo eroja tokun kuna dada, ao fa da sinu ikoko aseje, ao fi igi apere ge igbin yi si ona mesan, fun okunrin, ao ge si ona meje fun obinrin, ao ko si inu ikoko aseje yi ni ori awon eroja ti alo da sinu re, ao se ni aseje pelu epo ati iyo, ti aseje yi ba jina tan ao so si ori osuka kan, ao wa fi iyere osun te odu ifa ejiogbe si atelewo wa osi, ao wa pe ofo,re, si,…… OFO,RE,………. ASAKATAMAGBA NI ORUKO TI ANPE IWO IKU, ASAKATAMAGBA NI ORUKO TI ANPE IWO ARUN, ELEMOKA ONAPA, NI ORUKO TI ANPE IWO SANPANA, IWO NI EJI WEWE TI PA ODE NI GBO NI ONA OKO, OKUNRIN, TABI OIBINRIN TABI OMODE TABI AGBALAGBA TABI ELEBO TABI ONISEGUN TABI AJOGUN TABI WOLI TABI PASTOR TABI ENIKENI TI OBA NPE ORI EMI ………………… OMO………………. NIBI ONA ODI ONA ODI NI KI WON MA GBA LO SI ORUN, NITORIPE ONA ODI NI MO GBA YO IGBIN JE, ONA ODI TI MO GBA YO IGBIN JE, NI KI WON MA GBA LO SI ORUN, ao wa da iyere osun ti afi te odu ifa ejogbe ti ape ofo si yi sinu aseje yi, ao wa je gbogbo re tan patapata lekan soso, ODAJU BIKU,

IFA ATUDE TODAJU BIKU

Ao wa epo obo ati ikun ojia, ati igi ansorin ati ata ijosin ati eru Alamo ati aidan ao gun gbogbo re papo, SISE,RE,…ao lo epo obo kuna dada, ati gbogbo awon eroja tokun kuna dada, ao wa po papo mo ose dudu, ao ma fi we , ODAJU BIKU,

IFA ASEJE OLA TODAJU BIKU

Ao wa ewe sawerepepe tutu ati igbo mimu die ati ewe efo gure tutu ati ewe tanagbowo ati ewe ela tutu ati iyere ao lo gbogbo re ao da sinu isasun, ao fi se edo malu ti age si [16] ti ati fi omi gbona bo jina dada, ao ko sinu re, ao se ni aseje pelu epo pupa ati iyo die, ti o ba jina aso si ori osuka ao wa je ODAJU BIKU,

IFA OSOLE OWO ASIRIBIBO TODAJU BIKU

Ao wa odidi eiye igun kan tope dada tutu tonifun ninu, ao gbe ju sinu ape, ao ko gbogbo owo ti ana pata bomole ao tun da igbo bomole ao fi odidi atare kan si legbe ao jopo, ao lokuna dada, ao ro sinu igo kan, ao ma fi fo eko elewe mu larolaro, ODAJU BIKU,

IFA EYONU OMO ARAIYE TODAJU BIKU

Ao wa opolo gbigbe merindinlogun,[16] ati odidi atare merindinlogun, [16] ao jo papo, ao ma fi fo eko elewe odidi kan mu larolaro, ODAJU BIKU,

IFA EYONU ASINA OWO TODAJU BIKU

Ao wa ewe eyinolobe tutu ati ewe rere ako ati abo tutu, ati ata ijosin, merindinlogun,[16] ati oga gbigbe kan, ao lo gbogbo re papo, ao fi se eja aro gbigbe meta se la seje, pelu epo pupa ati iyo, ODAJU BIKU,

IFA IMULE AWON ELEIYE TODAJU BIKU

Ao wa eyin ibile to mo dada kan, ao ao fi omi gbona bo jina, ao wa rora bo epo ara re ti ibi Kankan oni shi lara eyin yi mo epo eyin yi lara, ao bo arawa si ihoho omoluabi, ao wa fi iyere osun te odu ifa ejiogbe si ilele, ao kan epo pupa le lori nibi oju iho Kankan awon odu yi, ninu yara wa ni ihoho omoluabi, ni awa ni kan soso ninu yara ni agogo kan oru [1am] ao wa fi eyin yi le ori odu ejiogbe ti afi iyere sun te si ilele ti akan epo si oju re yi, ao wa ka owo wa mejeji seyin, ao kunle si waju odu ejiogbe ti ate sile yi, ni ihoho omoluabi ao je eyo atare mesan lenu, ao wa pe ofo,re…. OFO,RE…. AYINI KITIKITI NI ORUKO TI ANPE IKU, [3Xtimes] OLOKITI KALE NI ORUKO TI ANPE ARUN,[3Xtimes] AGO FERE MONI LAYA LOGONJO ORU NI ORUKO TI ANPE IWO APETA,[3Xtimes] AFEFE LASO ADAN,[3Xtimes] ODUN NI ASO AWON IYAMI,[3Xtimes] IYAMI KILO ODUN KI ARA RO ADAN, EYIN IYAMI ALAGOGO ESU, EMI…………………….. OMO…………………… WA BAYIN MULE LONI O, IMULE TI MO WA BAYIN MU LONI, KI SE IMULE KA JO PIN ERAN ENIYAN JE, KI SE IMULE KI AJO PIN EJE ENIYAN MU, KI E MA PA OMO MI, KI E MA PA AYAMI O, KI E MA SE DAMI O, KI E WA SHI ILEKUN OWO NLA,NLA ATI IRE NLA.NLA FUN EMI…………………… OMO …………………….. LATI ONI LO, KI EJE KI OKIKI MI MA KAN KA KIRI AIYE ATI KA KI RI GBOGBO ORIGUN MERERIN AIYE KIN DI OLOWO REPETE , ao wa fi enu gbe eyin yi je, ao fi ahon wa la iyere osun ti ti afi te ejiogbe si ilele yi patapata lekan na,[IKILO PATAKI …. ti aba ti je aseje imule yi tan akogbodo sun mo obinrin fun odidi osu kan gbako, beni ako gbodo ba won je eyin abo laiye mo, ODAJU BIKU,

IFA OKIGBE ADA ATI OBE TODAJU BIKU

Ao wa ewe osenpetu tutu eyo kan, ati omo atare kan, ao je lenu kuna, dada ao gbe mi, odaju ti won ba sha wa lada lojona koni wole, yio kan le bi igba ti won na wa lore nio, ODAJU BIKU,

IFA OKIGBE TODAJU BIKU

Ao wa eso werenjeje mokanlelogun,[21] ati eyo atare mokanlelogun,[21] ao lo kuna lo ri olo ao fi sin gbere monkanlelogun, mokanlelogun, [21] si apa otun, [21] si apa osi, ODAJU BIKU

IFA ASOKO TI KI JE KI AWON AGBA BA OGUN WA JE TODAJU BIKU

Ao wa egbo etiponlola ao lomo eyo atare kan, ao ko sinu owu etutu ao di ni ikobiri pelu owu dudu ati funfun ao wa so ko enu ona ile ise wa nibi ti atin jo ogun odaju gbogbo ogun ti aba se awon agba oni le baje won koni le ti oju bo ise wa, ODAJU BIKU,

IFA FUN OMODE TABI AGBALAGBA TON TO SI ILE TODAJU BIKU

Ao wa isu jije [YAM] ati ito ajito idi eni yi, ao ro sinu igo kekere kan, ao sun isu yi ni ina toba jina, ao wa gun bi iyan ninu odo, bi aban gun lowo ao ma ta ito yi si die die ao ma gun, ao ma ta ito yi sinu re die die titi ti yi o fi di iyan ti ao fi gun tan, ti oba ti di iyan, ao ko sibikan, eni tonto si ile yi yio ma fi obe je iyan yi,lale sun ODAJU BIKU,

IFA EYONU AWON AGBA TODAJU BIKU

Ao wa ewe ajeobale tutu funfun [201] ati eso ewe iyalode funfun [201] ati epo obo topo die, SISE,RE……ao lo epo obo kuna dada ao po,papo mo ose dudu, ao wa ko ose ti apomo epo obo yi sinu odo, ao ko awon eroja tokun le lori, ao gun gbogbo re papo mo, ose yi, ninu odo dada, ao ko ose yi sinu igba tabi ike olomori kan, ao ma fi ose yi we nigbakugba, ODAJU BIKU,

IFA TI OKO OKUNRIN FI NGUN DADA TODAJU BIKU

Ao wa abeyo ogede agbagba, ao je ko yo ni dede gungun bi aba se fe ki oko wa gun to, ati igori mariwo ope, ao ge ni dede abeyo ogede ni dede kan, ao lo ti yio kuna dada, ao wa fo eyin ororo kan, si inu ike oni deri kan, ao wa da eyi ti alo kuna sinu re, ao po papo dada, ao wa pomo ori dada, ao ma fi wo oko wa, nigbakugba, ODAJU BIKU,

IFA ADABI PADA TODAJU BIKU

Ao wa ata isenbaye ati ewe apada tutu ati odidi atare kan, ao jo papo, ao lokuna dada, ao wa da eru inu aro papo mo, ao gun mo ose dudu, ao ma fi we larolaro, ODAJU BIKU,

IFA AFORAN TODAJU BIKU

Ao wa awo igala to fe dada pelu odidi atare kan, ao jo papo, ao lokuna dada ao ro sinu ado kan, ao wa gbe ko si ara ogiri kogbodo kanle mo, LILO,RE ao bu die si atelewo wa osi, ao wa te ni odu ejiogbe, ao wa pe ofo,re si,..OFO,RE… ERU KU OWO E GBE,[3X,times] IWOFA KU OWO OLOWO RE RORUN ALAKEJI,[3X,times] WON SA OMO ALAAKE LAAKE,[3X,times] WON TA OMO OLOFA LOFA,[3Xtimes] WON YIN OMO OYINBO NI IBON NI ORAN BADE,[3Xtimes] NI WON BA RANSE PE ETU BELEJE INU IGBO KOWA BA WON TAN ORO NA, ETU BELEJE DE BE KORI ORAN NA TAN,[3Xtimes] NI WON BA RANSE PE EFON GAGARA ILE ODAN,KOWA TAN ORO NA, EFON GAGARA DE BE KORI ORO NA TAN,[3Xtimes] NI BA RANSE PE AGBORIN ABIWO LORI SARASARA, KO WA TAN ORO NA, AGBORIN ABIWO LORI SARASARA LOWA GBON ORO NA DANU LORI ……………………..OMO ………………. LATI ONI YI LO, AGBORIN ABIWO LORI SARASARA WA BAMI GBON [ao daruko ejo na ati awon ti aba se ejo yi] DANU PATAPATA, KOMA LOJUTU MO, ao wa fenu fe ebu ti afi te ejiogbe sori atelewo wa yi, danu, ODAJU BIKU,

IFA AWURE ITAJA TODAJU BIKU

Ao wa ewe isu anamo, ao gun papo mo ose dudu, ao fi omi odidi agbon popapo dada, ao wa ko sinu ike olomori kan, ao fi omori re depa, ao lo rimo ori akitan ti won da ile si dada, fun odidi ojo meje gbako, leyin ojo meje, ao lo hu jade lori Akitan yi ,ao gbe wa si ile wa ao ma bu we larolaro, ODAJU BIKU,

IFA ASEJE BASIRI OWO TODAJU BIKU

Ao lo ja ewe abamoda tutu, merindinlogun,[16] ao ma da ba bi aba nse ja ewe yi ao ko mejo tele isasun tuntun, ao ko eyin ororo merin le lori, ao wa ko ewe mejo tokun le ori awon eyin yi, ao se jina lai fi omi si rara AKIYESI PATAKI. Ao ni fi omi si rara o, omi ti owa lara ewe yi ni yio se eyin yi jina ti oba jina, ao so si ori osuka kan, ao wa se [IWURE,ADUA] si dada ao bo epo eyin mererin ao je, ao wa ko gbogbo epo eyin yi ati gbogbo ewe ti afi se eyin yi si ori olo ao lo kuna dada, ao wa po papo mo ose,ao ma fi we, ODAJU BIKU,

IFA ERO FUN GBOGBO TESHO TODAJU BIKU

Ao wa eku asirin tope dada kan ati iseta ni iwonba ati kokoro ikomudu die ati ewe osan wewe die, ao gun papo mo ose dudu ti yio kuna dada, ao wa le ose yi mo ara ogiri, ao fi abere iranso topo die gun ose yi ni ara ogiri , ao ma bu ose yi lara ogiri ao ma fi fo oko wa, ti teso bawa lara obinrin na ko ni se wa ni nkankan, aburu Kankan oni se wa, ODAJU BIKU,

IFA FORI FOGO TODAJU BIKU

Ao wa eso osenpetu mesan[9] ati eyo atare mesan [9] ao ko si arin atelewo wa ao wa jin owo wa ni koto, ao wa tu oti chinapp die si ao wa da senu ao gbemi, AKIYESI PATAKI…… kogbodo kan eyin wa, ODAJU BIKU

IFA EBE AWON ELEIYE TODAJU BIKU

Ao wa okete kan tutu oojo ati imi ojo pupa topo die, ati eru alamo topo die, ati kerewu topo die, ati adan onigun ati ewe ajeobale tutu topo die, ati egbo tude topo die, ati odidi atare kan, ao ko gbogbo re sinu ape, ao jopo, ao lokuna dada, ao ma bu die die fi fo odidi eko elewe kan mu, odaju saka gbogbo idekide toba wa lara ni yio tu danu, ODAJU BIKU,

IFA AJERA TODAJU BIKU

Ao wa ori pepeye ati ese re mejeji ati ewe alupaida tutu ati odidi atare kan, ao jo papo, ao lo kuna dada, ao fi sin gbere yika orun wa mejeji, odaju saka pe bi eniyan ba je ogun buruku koni ran rara, ODAJU BIKU,

IFA ASINA TODAJU BIKU

Ao wa esolara pupa ati ewe ewuro tutu ati odidi atare kan, ao jo papo,,ao lokuna dada, ao ma fi fo eko elewe odidi kan mu ni alale, ODAJU BIKU,

IFA OUNMO IWOSE TI KI TASE FUN ALUFHA, WOLI, PASTOR, BABALAWO, ONISEGUN, TODAJU BIKU

Ao wa ori olongbo tonirun kan [1] ati ori eiye owiwi kan [1] ati ori ekute ile kan, ti won pa si oju ona nita gbangban [1] ati ori eiye karo kan, ati odidi atare kan, ao jo gbogbo re papo, ao lo kuna dada, ao wa ro sinu ado kekere kan, ao koko fi fo eko elewe mu ni alale fun odidi ojo meje gbako, lai ni ye, ao wa so ado yi mo oke ile ise wa, tabi ni ibi ti ati nda awon alejo loun, ao ma lo ni ekankan leyin ti ati lo fun odidi ojo meje gbako,……………… [ODAMILOJU]……………pe gbogbo nkan ti oba wa ni okan onibara wa ti oba ti de iwaju wa ao ma mo,gbogbo ero okan re, ati nkan to bawa si odo wa ODAJU BIKU

IFA OUNMO IRIRAN TI AFI RI GBOGBO NKAN TOPAMO NINU ALAMORI OMO ENIYAN TODAJU BIKU

Ao wa oju aparo mejeji tutu, ati oju ikun tutu mejeji, ati kokoro tanatana mokanlelogun, [21] ati oju olongbo tutu mejeji, ati ipin oju aja mejeji, ati ipin oju aguntan mejeji, ati oju eja [AKARABA, SHARK, TUTU] mejeji, ati oju eiye akala tutu mejeji, ao lo gbogbo re papo, ti yio kuna dada, ao fi die sin gbere kan kan si isale oju wa mejeji, ao po eyi to ba sekun mo ose dudu ao ma fi fo oju wa leyin ojo keje [7] ti ati sin gbere yi, ……………. [ODAMILOJU]…………….. pe gbogbo ounje ti eniyan to wa ni waju wa baje, ao ma ri kedere ni, bi aba koja legbe sare oku, ao mari oku yi kedere ati ibi to kori si, gbogbo alamari eda lao ma mo, ODAJU BIKU,

IFA OUNMO OKAN TOGBONA TODAJU BIKU

ao wa eku ago kan [1] ati eiye ega ako kan, [1] iye akala mesan [9] ati odidi atare meta [3] ao ko sinu ape,ao jo gbogbo re papo, ao lokuna dada, ao wa ro sinu ado kan,ao fi esunsun igi kan di enu ado yi, ao wa tun ju ado ti aro ebu si ti afi igi esunsun di lenu yi sinu ape, ao tun ko ewe etiponla merindinlogun ati odidi atare kan le ori ado yi ninu ape, ao ajo papo mo ado yi, ao lokuna, ao tun wa ro ebu ti ajo

yi sinu ado miran ni elekeji, LILO, RE,…….. ao ma to ebu ogun yi si ori atelewo wa osi ni ale patapata nigba ti aba fe sun, ao pe ofo re si,..OFO,RE,…… EKU NI RINU EKU, EIYE NI RINU EIYE, BI ADO BA GBE ADO MI WON RINU ARA WON, BI OKU BAKU LAIYE , AKALAMAGBO AGBE ODE ORUN MO, GBOGBO NKAN TI OBA FE SELE SI EMI…………………..OMO…………………. ABI ENIKENI TI MO BA GBERO LATI MO ALAMORI RE, KI NMA MO NI KIAKIA …….[ODAMILOJU] BI ABA KOJE LEGBE SARE AO RIBI TOKORI SI, ODAJU BIKU,

IFA OLUGBOHUN TODAJU BIKU

Ao wa iwo malu nla kan, ao bo epo ogede to de dada, ao ko tele sinu iwo yi,ao mu ako alangba ooye kan, ao na sinu iwo malu yi gboro, ti yio kori soke ninu iwo malu yi, ao wa lo ja ewe abamoda tutu oojo onigamarun mokanlelogun.[21]ao lo ti yio kuna dada, ao wa pomo ose dudu, ao bu ose yi die ao ko si ori ako alangba yi ninu iwo malu yi, ao le ose yi mo lori, ao tun ju opolo ijokun ooye kan sinu iwo malu yi, ao tun bu ose ti apo papo mo ewe yi die, ao tun lemo ori opolo yi ninu iwo malu yi, ao tun mu alakan ooye kan, ao tun ju sinu iwo malu yi, ao tun bu ose ti apo mo ewe ti alo yi die, ao tun lemo alakan ooye yi lori mole ninu iwo malu yi, ao tun mu oga ooye kan, ao gbe ju sinu iwo malu yi, ti yio kori soke ao wa mu ose tokun ti apo mo ewe ti alo yi, ao tun fi di oju oga ooye yi loke pa patapata, wa fi aso pupa we iwo malu yi lori, ao gbe lo sinu igbo, ao gbe ile ti yio jin die, ao gbe sinu iho na, ao wa fi ikoko nla kan de mole, ao da iyepe bomole, fun odidi ojo mesan gbako, leyin ojo kesan, ao lo sinu igbo yi ao lo hu jade,….[AKIYESI PATAKI],…. ao ti mu igi nla kan to gun dada die dani ti abati wa iyepe ori ikoko ti afi de mole kuro tan, igi yi ni ao fi shi ikoko yi, kuro lori re, leyin ise ju mewa ti ategun ti fe si ti oru re ti kuro, ao mu akuko adie kan, ao du eje re si ori olugbohun ti ari mole yi, ti eje adie yi yi ti ro si ori olugbohun yi dada ,ao tun irun abiya adie yi mejeji ao lemo gbogbo ara olugbohun, [AO WA FUN OLUGBOHUN YI NI ORUKO TOBA WUWA ,AO DARUKO RE NI [EMETA 3X,times] PELU SI SOPE [LAGBAJA OOOOOO, GBOGBO NKAN TI MOBA TI SOPE KO SE NI KO SE O, ISE TI MO BA TI RAN O, NI KO MA JE,O, EYI TI MIO BA RAN OGBODO SE O,] ao je ki ategun fe si die ki eje ati awon irun adie yi gbe mo lara leyin ti ati fun ni oruko to wuwa tan, ao wa gbe lo si ile wa tabi ninu ile agbara wa, ao gbe sinu odo, LILO, RE,….. ao ma lo si ibi ti agbe olugbohun yi si, ao wa ma pe oruko olugbohun yi [lemeta,3X,times] ao wa so ikan ti afe ko sele tabi iru ise ti afe ran, [AKIYESI PATAKI]………. AKOGBODO GBAGBE ORUKO TI ABA FUN OLUGBOHUN YIO,….. BIBEKO OLEWU OO, ….[ODAMILOJU] gbogbo oro ti aba so ase ti gun niyen, sungbon beru olohun ko si ranti ojo atisun o, ma fi se ika o, ODAJU BIKU,

IFA OKIGBE TODAJU BIKU

Ao wa ewe ajeobale tutu oojo, ti ko ya rara tabi dalu rara, merindinlogun, [16] ati eyo atare merindinlogun, 16] ….. SISE,RE… ao mu eyo ewe kan, ao fi eyo atare kan, lelori, ao tun fi ewe miran le lori, ao tun fi eyo atare kan le lori, ao tun mu ewe miran si ori eyo atare yi, ao tun fi ewe miran le lori,….. be la se to lori aranwon ni ewe kan atare kan, titi ti yio fi pe ewe merindinlogun [16] ati eyo atare merindinlogun, [16] ao wa ran lawo,ikorun tabi igbadi, sungbon akogbodo ran lawo ewure,o, ao ma de onde yi, mo apa abi kafi korun, ki amu obe tomu dada kafi dan arawa wo [ODAMILOJU] pe obe na koni ge wa, sungbon yio le gege bi igba ti won na wa lore ni o, ODAJU BIKU

IFA OSE OSOLE OWO TODAJU BIKU

Ao wa apata abalaiye ati okete tutu kan, ao gbe apata yi, ao fi oti chinapp fo ni gbogbo ara dada, ao wa gbe apata yi ju sinu ape tun kan, ao wa du okete yi si ori apata yi ninu ape, ao ko eran okete yi le ori apata yi ninu ape, ao wa ko ewe awedewerisa lelori, ao wa lo ja ewe ewuro oojo ti ko kanle lelori mole ninu ape, pelu odidi atare kan ao wa jo gbogbo re papo, ao lo kuna dada, ao ro sinu sere kan, ao fi nkan, di lenu pa. ao wa kan posi iroko kan, ao gbe sere yi sinu re, [ETUTU, RE,] ao ma ro ekuru funfun sinu awo funfun kan, ao ma gbe si egbe sere yi ninu posi iroko yi, fun odidi ojo meje gbako, leyin ojo meje, ao ma to ebu inu sere yi si ori atelewo wa die die, ao ma fi hoti to lagbara lo, pelu pipe ofo,re,….. OFO,RE…..ERAN NLA NI MO FI SE ETUTU FUN YIN KI ELO MU ENIYAN, NLANLA WA FUN MI, TOWO TOWO OWO WON KI WON WA FI SE EMI …………………. OMO………………… LANU O, ODAJU BIKU

IFA OSOLE TODAJU BIKU

Ao wa ewe aje tutu oojo, ati ewe akinsan tutu oojo, ati eiyele funfun kan, ao lo gbogbo ewe yi papo mo iyere merindinlogun [16] ao ko da sinu isasun kan, ao pa eiyele yi, ao ge si wewe, ao ko sinu isasun, pelu awon nkan ti alo yi, ao fi epo ati iyo si, ao se laseje,ti aseje yi ba jina toba tutu, ao te aso funfun opa kan kale, ao so aseje yi sori aso funfun yi, ao jo ko sori aso funfun yi, ao se adua si ao wa je aseje yi, [TI OBA WU WA, AO PA OBI OLOJU MERIN KAN] fun aseje yi, ao fi obi yi se sara ODAJU BIKU

IFA AWORO TODAJU BIKU

Ao wa ori ofafa nla kan to nirun dada ati iru woro topo dada ati odidi agbon nla kan to lomi ninu dada, ati odidi atare kan, .. SISE, RE…… a o gbe ori ofafa sinu ape kan, ao ko iru woro topo bomole ao ju atare kan si legbe ao jo papo, ti aba jo tan ao lokuna dada, ao mu agbon yi ao rara lu ni ibi ori re, ni ibi oju re die, ao tu omi inu agbon yi danu, ao wa ro gbogbo ebu ogun ti ajo yi sinu agbon, ati ito aji to, idi eni to ni ise yi, sinu agbon yi, pelu ebu ogun ti ajo yi, ao fi nkan di oju agbon yi pa, ti koni jo, ao wa lo gbele si enu ona shop, abi ibi ise abi nibikibi ti afe ki ero ma ya, ao rimo enu ona abawole nibe, ODAJU BIKU

IFA AWORO TODAJU BIKU

Ao wa irun ori omo tunutun ojo mejo [8,days] ati emo agbo ati emo ajao, ati ewe rere ako, ati ewe rere abo pelu odidi atare kan, ao jo papo ao lo kuna dada, ao pomo ose dudu ao fi omi ti won fi we omo na po ose yi dada, ao ma fi we ao ma fi won ile shop, wa tabi ile ise wa tabi ile itaja wa ODAJU BIKU,

IF AOWO, RESPECT TODAJU BIKU

Ao wa ewe owo tutu ati oguna kan ati owu dudu ati funfun, SISE,RE…. ao mu oguna to pon dada kan ninu ina, ao ju sinu omi, ti oguna yi ba tutu, ao mu oguna yi, sinu ewe owo yi, ao wa ewe yi mo ara oguna yi, ao wa fi owu dudu ati funfun di ni ikobiri ti ibi Kankan oni han si ta la ra re, ao ma ju si apo jade, ODAJU BIKU,

IF AOWO, RESPECT, TODAJU BIKU

Ao wa orogbo kan ao panipansa, ao wa yo okan ako alangba ni ooye, ao sare ju sinu orogbo yi, ati eyo koro atare meje [7,fun obinrin] eyo atare mesan, [9,fun okunrin] ao wa fi ideri orogbo yi de pada, ao wa gbe sinu efe owu, ao di ni ikobiri, pelu owu dudu ati funfun, ao wa lo ran ni awo ijimere ,ao ma ju sapo wa jade tabi kama ju sinu motor, tabi ka ran ni onde ao ma so mo ibadi, ODAJU BIKU

IFA TI AFIN YO OMO TOBANI EGBE ORUN KURO NINU EGBE TODAJU BIKU

Ao wa olongbo dudu ooye kan, ti ko ni aba won Kankan lara, ati ewe ogo tutu ati oko atare kan SISE, RE,… ao ko ewe yi sinu ape ati oko ata re kan, ao gbe so ri ina ti ape yi ba ti gbona jonjon gidigidi, ao mu olongbo dudu yi, looye ao gbe enu si leti otun ao daruko eni ti afe yo kuro ninu egbe si leti pe[IWO OLONGBO DUDU YI MO RAN ELEDA RE NI ISE SI AWON ELEGBE ……………….. OMO……………….. PE KI WON YO KURO NINU EGBE, KI WON KO KALE, NINU EGBE RE] ao tun se be si eti osi na be, ao wa si ape yi ao ju olongbo yi sibe looye, sungbon ao wa aso kan ti ao fi gba ape yi mu gidi, bibeko yio danu ti ape yio si fo danu nitoripe olongbo yi yio japoro, ao jopo, ao wa lokuna ninu ape, ao wa da ebu ogun yi si ona merin,ao fi idakan po ose dudu, eni ta fe yo kuro ninu egbe yi, yi o, ma fi we, ao po idakeji papo mo lofinda bintu eni ti afe yo kuro ninu egbe yio ma fi para ti oba we ose yi kogbodo nu ara titi ti omi iwe ara re yio fi gbe mo lara, leyina yio fi lofinda yi para, ao wa po idaketa mo ekuru funfun, ti koni iyo, ao fon da si iwaju ita ile lale pelu iwure pe ki won yo eniyi kuro ninu egbe, ebu idakerin awa gangan ti ase ise yi fun yan, awa gangan yio ma fi fo eko mu, [AKIYESI,PATAKI… nitoripe toba kuro ninu egbe tan awon elegbe re tokun yio fe gbe owo ija siwa, lati bawa ja, sungbon ebu ti atin fi fo eko elewe mu yi koni je ki awon egbe re le se nkankan fun wa koni jeki agbara won ka wa, ODAJU BIKU

IFA ISOYE NLA TODAJU BIKU

Ao wa eja ojiji oye kan ati mariwo ope, ati ikode gidi ojulowo kan ati iye agbe kan, ati iyere topo die, ati eran die, ati odidi atare kan, ao ko gbogbo re sinu ape, ao jo papo ao lokuna dada, aoro sinu igo olomori funfun kan, tabi ado kan, ao fi igi di enu ado yi, LILO,RE… ao to ebu die si ori atelewo wa osi, ao te ni odu ifa [OBARA…IROSUN]… obara lapa otun,, irosun lapa osi] ao wa pe ofo,re si,.. OFO,RE… ERAN KO MA RAN EMI…………………… OMO……………… LETI GBOGBO ORO TI ,MO BA GBAGBE,[3Xtimes] ALATO NI ORUKO TI ANPE IWO ATARE GBOGBO ORO TI EMI…………………… OMO………………. BA GBAGBE KO MA TO SI MI NI OKAN[3Xtimes],MINIMINI ALA OWO RE PARI NI ORUKO TI ANPE IWO IYERE GBOGBO ORO TI EMI ………………… OMO………………. BA GBAGBE KOMA FI YEMI YEKEYEKE,[3xtimes] IFA OBARA ROSUN NI IFA KIFA TI KO OMOLOMO NIYE LO, WA KO IYE TE MI WA FUN MI O, ao wa to oyin gidi lelori ao tola ODAJU BIKU

IFA OWO RESPECT TODAJU BIKU

Ao wa egbo apasan ati eyo atare mesan [9] ao ko sinu owu etutu ao di ni ikobiri pelu owu dudu ati funfun, ti aba fe danwo bo ya osise ao se kopo dada ao ju sinu oguna eyokankan eyi toba jona ko sise niyan, eyi ti ko ba jona ao mu ao ma ju si apo wa jade ODAJU BIKU

IFA AWEBI WEPE DANU TODAJU BIKU

Ao wa ewe bomubomu tutu ooojo ati epo obo, SISE,RE… ao lo epo obo kuna dada, ao po papo mo ose dudu, ao tun lo ewe bomubomu kuna dada, ao wa tun pomo, ose ti apo epo obo mo yi, ao ko sinu ike olomori kan, ao depa ao mu eiyele fufun toni emi dada dani ao bu ose yi die dani, ao wa lo si odo ton san dada, [AKIYESI,PATAKI…..TI ABA DE ODO YI AO BO GBOGBO ASO WA, AO WA NI IHOHO OMOLUABI, AO KORI SIBI TI ODO YI SANLO, AO MU EIYELE YI, AO GBE ENU SI NI ETI AO SE [IWURE ADUA] ITUSILE SI NI ETI, AO TUN SEBE SI ETI OSIN KELEKELE, AO MU EIYELE YI LA O FI SE KAINKAIN, TI AO FI WE OSE YI, BI ABA FI LE WE OSE YI, TAN TI EIYELE YI, ,O, KU, AO JU EIYELE FUNFUN YI SOKE, AO FI EIYELE SI LE, KO MA FOLO, BI EIYELE BA FI LE FO,LO, IRE NLA DE, SUNGBON BI EIYELE YI BA FILE KU MO WA LO WO, KATUN MURA GIDIGIDI NITORIPE OLEWU OO, GBOGBO ASO TI ABA WO LO SI ODO YI, AO BO KALE NIBE, AO WO ASO MIRAN PADA SI ILE, LAI WO EYIN WO, ODAJU BIKU,

IFA AWURE ASIRIBIBO TODAJU BIKU

Ao wa oga gbigbe meta ao lo kuna dada, pelu igbo mimu die bintin, ao ro sinu igo kan pamo ao fi omo ri re depa, ao ma bu fi ro iresi sisise funfun lasan ti koni epo tabi ata ninu, ao ma fi ebu yi ro iresi yi je, ODAJU BIKU,

IFA OSE EYONU TODAJU BIKU

Ao lo ja ewe ewuro tutu oojo ati ewe omisinmisin mejeji, ao ko sori olo, ao lopo ti yio kuna dada, ao po papo mo ose dudu pelu ori, ao ko sinu igba onideri kan, ao ma fi we nigba kugba ODAJU BIKU

IFA KI OFA MARAN WA TODAJU BIKU

Ao wa eso werenjeje mesan [9] fun kunrin],meje fun obinrin [7] ati eyo atare mesan [9] fun okunrin,] meje fun obinrin]ati ako okuta die ao lo gbogbo re papo ti yio kuna dada, ao fi sin gbere mesan fun okunrin ni aya ati eyin, mesan [9,9,]fun okunrin,] gbere meje meje fun obinrin ni aya ati eyin [7,7.] fun obinrin, ODAJU BIKU

IFA OSE EYONU TODAJU BIKU

Ao wa ewe omisinmisin mejeji ati ewe anu tutu, ao lo gbogbo re kuna dada, ao pomo ose dudu, ao tu lofinda bintu le ori ose yi, ao po papo mo ose dada, ao ma fi we ni idaji kutukutu haihai ODAJU BIKU,

IFA ISIJU TOGBONA TODAJU BIKU

Ao wa ole inu ewure ati ewe mojukuro tutu oojo ati ewe alaifohun tutu oojo ati ekuro olomo meta, ati odidi atare kan, ao di oju mo agbari ao bu sakiti isale aro, SIAE,RE,…. Ao ko gbogbo re sinu ape ao jo ninu okunkun ni arin oru [AKIYESI PATAKI] akogbodo tan ina jo ogun yio, inu okunkun ni ao ti joo,] ao da akerengbe kekere kan lu lebu ni roboto, ao ro ebu ogun ti ajo ninu okunkun yi sinu akerengbe yi, ao wa pe omo kekere kan ti koi ti balaga pe ko wa bawa wo inu akerengbe yi, ao bi omo na lere pe ki ni nkan to ri ninu akerengbe yi, ti omo yi ba ti dawa loun pe oun ko ri nkankan ninu akerengbe yi, ao wa fi esunsun igi kan di enu akerengbe yi , ao gbe ko si ara ogiri, LILO,RE,…..ao to die ninu ebu inu akerengbe yi si ori atelewo wa, ti afi te ifa ejiogbe si owo wa, ao wa pe ofo, re si ..OFO,RE….. BI ERIN BAJI ERIN AFI EYIN LU EYIN KEKEKE, BI EFON BAJI, EFON AFI IWO LU IWO GBAGBA, EMI………………….. OMO…………………….. DI EIYE ONIPERE TI ONM NFO PERE JA PERE, EMI……………… OMO………………… DI OGAN ERUJU TI MANFO PARAMO PARAMO, OUN LO DIFA FUN AWON OLOJA MERINDINLOGUN ONI TIN BA DO AYA ALARA, KI NMUJE, TIN BADO AYA AJERO KIN MUJE, TIN BA DO AYA ORANGUN ILE ILA, KIN MU JE O, OBEKE LONI, TI E BA RIMI KI E MA KI MI, ALOIFOHUN LONI TIE BA RIMI KI E MA LE FOHUN LONI KI ESA MA WOMI SUN NIO, MODI AWO SUN NITORIPE AWO SUN NU EKUN WO, AGBIN SINU NI EKUN NGBIN, NIBI TI MOLO YI ATI OKUNRIN ATI OBINRIN ATI OMODE ATI AGBA KIWON MA SE RIMI O,] ao fi die sa ori wa, eyi tokun lowo wa ao fi fo eko elewe mu, ki ato jade kuro ni le, ODAJU BIKU

IFA FUN TI OMO BA JOKO TABI DEBU SINU ALABOYUN TI YO FI YI PADA TODAJU BIKU

Ao wa eso dagba tabi eso aso feyeje eyo kan ao lo pomo iyere ao fa da sinu isasun aofi se eja aro gbigbe je lepo niyo ODAJU BIKU,

IFA INU RIRUN FUN ALABOYUN LEYIN IBIMO

Ao wa ko koro atare topo dada si ori olo, ao lokuna dada, ao wa da sinu oti to lagbara yio ma mu ni gasi meji meji larolaro lai ti jeun, ODAJU BIKU

IFA ISIJU TOGBONA TI OJU KANKAN KOFI NI LE RI WA TODAJU BIKU

Ao wa koro omo inu ado, ati koro omo inu agbe ati koro omo inu elegede ati koro omo inu egusi ito ati koro omo inu egusi bara ati omo inu onigedegede, ati koro omo inu osan mimu, ati omo inu ayo tita ati iboju igbin ati oju adan mejeji ati oju odidere mejeji ati omo inu itagiri ati oju oromo die ati ewa jije pupa ati egbo gbegbe die ati aso iwaji dudu, ati irun ipako eni to fe ma lo ogun yi, ao yo aso iwaji yi pamo ao toju re sibi kan, ao wa ko gbogbo awon eroja tokun sinu ikoko ao jopo ti yi kuna dada Ao lo kuna dada ninu ikoko, ti aba jotan ao ro sinu ado kan ao fi esunsun igi di ado yi lenu, ao wa gbe ado yi sinu aso iwaji, ao fi aso yi di ado yi dada ti ibi kankan oni han sita lara ado yi mo, tabi kafi aso iwaji yi ran apo ka ma gbe ado yi sinu re, ao wa si omori ado yi kale, ao ma pe ofo re si ti aba pe ofo re si tan ao to ebu die ninu ado yi ao fi sa ori wa nibi ipako wa AKIYESI.. PATAKI..akogbodo de ado yio, ao shi enu ado yi, kale ni, titi ao fi jade lo, ti ao fi de pada, [ODAMILOJU] PE.. bi aba ti shi enu ado yi kale ti abu ebu ogun ti ape ofo re si, ti afi sa ori wa kosi enikeni ninu eda alaye ti yi fi oju riwa mo titi, ao fi lo ti ao fi pada de, OFO,RE…. OMO ARAIYEKI LOJU KI WON RI OMO INU ADO,[3Xtimes] OMO ARAIYE KI GBE INU AIYE KI WON RI OUN TI AGBE DI SI IKUN,[3Xtimes] BI EGUSI ITO BA SO AFI OMO INU RE PAMO FUN OLOKO,[3Xtimes] OMO INU ELEGEDE KI GBE INU ELEGEDE RIRAN,[3Xtimes] OMO INU BARA KI GBE INU BARA RIRAN,[3Xtimes] OMO ARAIYE KI RIDI OMO ONIGEDEGEDE,[3Xtimes] AKI FOJU WEYIN KARI IPAKO ARA ENI,3X,times]GBOGBO ARA NI EWA FI SE OJU KANKAN SI OLOKO,[3Xtimes] BI ADAN BA DORI KODO KIRI OLODUMARI,[3Xtimes] BI ODIDERE BA KA OWO SE YIN, KIRI ARA RE,[3Xtimes] BI GBEGBE BA TA EGBO KIRI OLUIGBO AFI DE ODE ORUN,[3Xtimes] BABALAWO KI WEJU KORI OMO INU OSAN WEWE,[3Xtimes] OJU ORO KI DURO SORI OMI KORI ISALE OMI,[3Xtimes]IBOJU IGBIN KI JE KI IGBIN

O RIRAN,[3Xtimes] ASO DUDU KI JE KI AMO ISE ASO,[3Xtimes] EMI …………………….. OMO………………… njade lo si ibi bai, [ao daruko ibi ti anlo ati nkan ti afe lo se ni be,ao sope ti ti ti ao fi lo ti mafi de ki oju Kankan ko ma se ri wa rara,] ao wa to ebu ogun yi ninu ado yi, ao bu sa ori wa lati iwaji ori wa losi ipako wa [IKILO PATAKI… ojokojo ti abalo asiri yi lati fi jale ojo na ni ile yio mu wa ti asiri yio si baje ti ko ni sise emo ODAJU BIKU